# Àwon Ẹ̀bẹ̀ Àdúrà Fún Ètò AGBAPA

1. Àdúrà ìwẹ̀ mímọ́. Pe ẹ̀je Jésù Kristì, kí o sì ri ara rẹ sínú rẹ̀. Matt. 26:28, 1John 1:7.

2. Jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀sẹ̀ rẹ tí o mọ̀ kí ẹ̀rí ọkàn rẹ́ lè mọ́ kósì múra tán fún Àdúrà. Heb. 10:22.

3. Pe Àwon ángẹ́lì mímọ́ sọ̀kalẹ̀ láti yí ọ ká, kí o sì sọ pẹpẹ rẹ di mímọ́. Heb. 12:22, Ex 29:37.

4. Fífii ìdàpọ̀ pẹ̀lúu pẹpẹ Amazing Grace hàn àwọn t'ọ̀run. Jẹ́ kí Ọ̀run mọ irúu ẹ̀yà tí o ti wá pé ti Amazing Grace ni. Num 1:4, Rom 11:1B, Rev 7:4-5.

5. Kí á gbàdúrà fún ìsọjí ìbẹ̀wò Ẹ̀mí Mímọ́ àti ti iná. Ìbẹ̀wo ẹnìkẹta nínúu mẹ́taalọ́kan tí yóò yọrí sí: (a) Ìrìbọmi Ẹ̀mÍ Mímọ́ àti ti iná 🔥 fún gbogbò wa. (b) fífii orísịiirísịi ẹ̀bùn t'ẹ̀mí dáwa lọ́lá, (c) ìpè sí onírúurú isẹ́ ti ẹ̀mí nínú ìjọ. Mat 3:11, Acts 1:4-5, 2:1-4; Joel 2:28-32, Eph 4-11-12.

6) Kí á gbàdúrà fún ìsọjí ogidì iṣẹ́ àmì àti iṣẹ́ ìyanu nínú ìjọ wa. Mark 16:15-18.

7) Kí á gbàdúrà fún ìsọjí iṣẹ́ ìyanu Ìwòsàn òtítọ́ nínú ìjọ wa. Acts 10:38, 1Cor 12:9.

8) Kí á gbàdúrà fún ìsọjí ìgbé ayé ìwà mímọ́ àti òdodo láàrín ìjọ wa. 1Thes 4;3, 5:23.

9) Kí á gbàdúrà fún ìsọjí nlá ti ìjèrè-ọkàn nínu ìjọ. Acts 2:41, 4:4, 5:14.

10) Kí á gbàdúrà fún ìsọjí nlá ti ibukun owó pẹ̀lú ọrọ̀ nínú ìjọ wa. Hag 2:8, Php 4:19, Eph 3:19-20.

11) Gbàdúrà ki Gbogbo ìde Sátánì lórí Amazing Grace kí ó máa já. Rom 8:38-39, Col 1:13-18, 2:13-15.

12) Àdúrá fún General Overseer (l'ára àti ní ẹ̀mí) 2Th 3:1-2,  Heb 13:18,  Mat 26:31.

13) Fa ẹ̀bẹ̀ àdúrà yọ nínúu àwọn ẹsẹ Bíbélì tí o ti kà l'ónìí.

14) Ṣiṣẹ́ l'óríi ẹ̀bẹ̀ àdúrà ti t'ara pẹ̀lú.

Àwọn wònyí ni a ó tẹjúmọ́ bi ìlépa wa bí a ti nlọ nínú ìrìnàjò mímọ́ ti AGBAPA fún osù May, 2023.

Kí Ẹ̀mí Mímọ́ fún wa ni ohún; olúkúlúkù wa yó sì dàgbà dé gbèdéke olórí ogun nínúu ogun Olúwa.

Àwon ẹ̀bẹ̀ àdúrà míràn lè dìde bí a tí'n lọ nínú ìrìn àjò AGBAPA, gẹ́gẹ́bi ọmọ ogun fún Krístì, ẹ jẹ́ kí á wà ní ìmúra sílẹ̀.

Àwa le se ohun gbogbo nínúu Krístì ẹnití nfi agbára fún wa.

-FILIPI 4 : 13